# ÀKÓJỌPỌ̀ ÀBÁJÁDE ILÉ-IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ LÓRÍ ÈTÒ ÌṢÚNÁ ÌJỌBA ÌPÍNLẸ̀ ÈKÌTÌ FÚN ỌDÚN 2022.

## 1.00 ÀMÚLÒ ÈTÒ ÌṢÚNÁ

- Ètò ìṣúná ọdún 2022 jẹ́ ètò ìṣúná èyí tí owó tó wọlé àti owó-iná yóò jẹ́ dọ́gba-n-dọ́gba iye owó tí a lérò pé yóò dín ní Bílíọ̀nù Mẹ́tàlélọ́gọ́fa Náìrá (₦122,699,039,657.27).
- Owó tó wọlé ní ọdún náà lé díẹ̀ ní Bílíọ́nù márùn-ún dín láàádóje Náìrá (₦125,368,446,931.23) nígbà tí owó ìná lé díẹ̀ ní Bílíọ́nù márùn-ún dín lọ́gọ́fà Náìrá (₦115,373,691,931.32) tó túmọ̀ sí àmúlò ètò ìṣúná tó jẹ́ ìdá méjìlélọ́gọ́rùn-ún nínú ida ọgọ́rùn-ún (102%) fún owó tó wọlé àti ìdá mẹ́rìn lé láàádọ́rùn-ún nìnú ìdá ọgọ́rùn-ún (94%) fún owó-iná
- Owó tí iye rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù mọ̀kàn-dín-láàádọ̀run-ún Náìrá (₦89,278,179,914.13) tó jẹ́ owó tó wọlé látìgbàdegbà nínú ètò owó ìṣúná tí iyé rẹ̀ dín ní Bílíọ̀nù mẹ́rìnlélọ́gọrin Náìrá (₦ 83,907,265,490.61) tó túmò si ìdá mẹ̀fà lé lọ́gọ́rùn-ún (106.%) èyí tí ó dín níye sí ti ọ̀dun tó kọjá ní iye tó lé díẹ̀ ni ìdá ọgọ́rùn-ún lé mẹ́sàn-an (109.80%) ti ọdún tó kọjá.
- Ọ́pọ̀ owó tó wọlé sí àpò Ìjọba Ìpínlẹ̀ ló jẹ́ owó tó wọlé láti àṣùwọ̀n Ìjọba Àpapọ̀ tí iye rẹ̀ lé ní Bílíọ́nù Márùn-ún dín lọ́gọrín (₦65,062,062,631,356.11) tó túmọ̀ sí ìdá tó dín díẹ̀ ní ìdá mẹ́tà lé láàádọ́rin nínú ìdá ọgóṛùn-ún (72.87%)
- Owó tó wọlé sápò Ìjọba Ìpínlẹ̀ láti ọ̀dọ̀ Ìjọba Àpapọ̀ gbé pẹ́ẹ̀li si láti iye tó lé ní Bílíọ́nù Méjì lé lọ́gbọ̀n Náìrà (₦31,661,430,473.00) ní ọdún 2021 sí iye tó dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù mẹ́rìnlélọ́gbọ̀n Náírà (₦ 33,943,555,767.00) tó lé ni ìdá méje (7.21%). ní ọdún 2022. Àpapọ̀ owó tó wọlé sápò Ìjọba Ìpínlẹ̀ lọ́dún tí a ń gbé yẹ̀wò yìí láti àṣùwọ̀n Ìjọba Àpapọ̀ lé ní Bílíọ́nù márùn-ún dín láàádọ́rin Náírà (₦65,062,631,356.11) èyí tó gbé pẹ́ẹ̀lì jú iye tó dín ní

Bílíọ́nù mẹ́rìnléláàdọ́ta Náìrá (₦53,720,548,410.00) tó wọlé ní ọdún 2021 èyí tí iye tó fi gbé pẹ́ẹ́lí si lé díẹ̀ ní Bílíọ́nù mọ́kànla (₦11,342,082,946.11) tó túmọ̀ sí ìdá tó lé díẹ̀ ní ìdá mọ́kànlélógún (21.11%).

- Owó tó wọlé lábẹ́lẹ̀ gbé sókè sí i ju ti ọdún 2021 láti iye tó lé ní Bílíọ́nù mẹ́tàlá Náírà (₦13,620,433,129.00) sí owó tó dín ní Bílíọ́nù mẹ́tàdínlógún Náírà (₦16,748,259,534.93) ní ọdún 2022. Èyí tí iye tó fi gbé pẹ́ẹ́lí si dín díẹ̀ ní ìdá mẹ́tàlélógún nínú ìdá ọgọ́rún-ún (22.96%) èyí tó gbé pẹ́ẹli síi láti Bílíọ́nù mẹ́rin dín díẹ̀ Náìrá (₦ 3,947,347,001.39) sí iye tó lé ní Bílíọ́nù Méje (₦7,467,289,022,83) tó túmọ̀ sí ìdá mọ́kàndínláàádọ́rún-ún dín díẹ̀ (89.17%).
- Owóyàá láti òkèèrè gbé pẹ́ẹ́lí sí i ní ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò ju ti ọdún 2021 láti iye owó tó dín ní Bílíọ́nù mẹ́fà Náírà (₦5,765,039,628.00) sí iye tó lé díẹ̀ ní Bílíọ́nù méje Náírà (₦7,002,174,689.79). Ní ọdún 2022, Owóyàá lábẹ́lé gbé sókè láti iye tó lé ní Bílíọ́nù mẹ́fa Náírà (₦6,075,112,034.63) ní ọdún 2021 sí iye owó tó dín ní Bílíọ̀nù Mẹ́tàlá Náírà (₦12,760,662,179.00) ní ọdún 2022. èyí tó jẹ́ (Owóyàá láti Bánkì àti Ètò Ìlànà ẹ̀yáwó fún iṣẹ́ àgbẹ̀ (Commercial Bank Loans, CBN Scheme, CBN Health Intervention fund).
- Iye Owó tó wọlé ní pàtó lọ́dún tí a ń gbé yẹ̀wò din ní Bílíọ̀nù méjìdínlọ́gbọ́n Náìrá (₦27,738,998,634.89) èyí tó yátọ̀ sí iye owó tó le ní Bílíọ́nù mọ́kànlélọ́gbọ̀n àbọ̀ Náìrá (₦31,561,774,166.66) tí a lérò pé yóò wọlé. Èyí tó já sí ìdá méjìdínláàádọ́rùn-ún (88.%) tí ó sì fi ìdá tó dín díẹ̀ ní ìdá mẹ́tàlá (12.89%) lọ sókè ju ti ọdún tó kọjá lọ tó jẹ́ ìdá tó lé díẹ̀ ní ìdá márùn-ún dín lọ́gọ́rin (75.11%)
- Owó-iná ní pàtó fún ọdún 2022 jẹ́ iye tó dín ní Bílíọ̀nù mẹ́rìnlelọ́gọ́rin Náìrá (₦83,780,390,112.53) tó jasi ìdá ọ́gọ̀rún-ún dín díẹ̀ (99.84%) àmúlò ètò ìṣúná. A ṣe àkíyèsí pé owó iná àtìgbàdégbà dín ní ìdá mejiléláàádọ́rin

(71.60.%) iye owó tó wọlé àti ìdá tó dín díẹ̀ ní ìdá mẹ́rìnléláàdọ́rùn-ún (93.84%) iye owó atìgbàdégbà tó wọlé ní pàtó ní ọdún ti à ń gbé yẹ̀wò.

- Owó-iná pàtó fún ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò lé ni Bílíọ̀nù mọ́kànlélọ́gbọ̀nNáìrá (₦31,593,295,818.79) tó jẹ́ ìdá méjilélọ́gọ́rin (82.%) ìṣàmúlò ètò ìsúná, eyi tó jẹ́ ìdá ọgbọ̀n (30.%) owó tó wọlé, ìdá tó dín díẹ̀ ní ìdá mẹ́rìnléláàádọ́fà (113.90%) iye owó tó wọlé pàtó àti ìdá tó lé díẹ̀ ní ìdá mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n (27.38%) iye owó ìná ni ọdún náà. Ní ọdún tí à ń gbé yẹ̀wò yìí, owó tí a lérò láti ná bí owó ìná àtìgbàdegbà jẹ́ ìpín 1:22, nígbà tí ìpín ní pàtó ní ọdún náà jẹ́ ìpín1:27. Àbájáde èyí ni pé ètò ìṣúná ti ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò dára ju ti ọdún tó kọjá lọ.
- Ilé Iṣẹ́ Ayẹ̀we owó-wò ṣe àkíyèsí pé ètò ìṣúná ti ọdún 2022 kò kúnjú ìwọ̀n tó torí pé owó tí wọ́n gbèrò pé yóò wọlé tó lé ní Bílíọ̀nù mọ́kànlélọ́gbọ̀n àbọ̀ Náírà (₦31,561,774,166.66) kéré níye sí iye owó tó dín ní Bílíọ̀nù mọ́kàndínlógójì Náírà (₦38,761,774,166.66). tí wọ́n gbèrò láti ná. Èyí túmọ̀ sí pé iye owó tó lé ní Bíḷíọ̀nù méje Náírà (₦7,200,000,000.00) tó lé ní ìdá méjìdínlógún àbọ̀ (18.60 %) ni wọ́n gbèrò láti fi kún un lára owó tó wà tẹ́lẹ̀.

## 2.00 ÀKÍYÈSÍ ÀTI ÀBÁ ILÉ-IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ LÓRÍ ÌṢÀMÚLÒ ÈTÒ ÌṢÚNÁ.

- Ó dà bí pé àbùmọ̀ iye tí ó máa wọlé nínú ètò ìṣúná tí kìí jẹ́ kí a lè kúnjú ìwọ̀n nípa ètò ìṣúná tí a tọ́ka sí tẹ́lẹ̀ ni wọ́n ti mójú tó nínú ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò yìí
- Iye owó-iná tí SFTAS ti ṣe àlàkalẹ̀ sí < ìdạ́ -márùn ún dínlọ́gbọ̀n àti ìdá ogún, àti ìdá márùn -–ún dínlógún <25% < 20% àti <15% fún ọdún 2019, 2020 ati 2021 ní ṣíṣẹ̀-ntẹ̀lé. ni o wá já sí ìdá mẹ́fà (6%) atí mẹ́rìndínlógún (16%) tí a gbèrò fún ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò.

- Ó ṣe pàtàkì láti wá àwọn ọ̀nà míìràn tí owó yóò fi máá wọlé kí owó tó-ń-wọlé sápò Íjọba lè búrẹ́kẹ́ sí i
- Kí Ìjọba Ìpínlẹ̀ ṣe àfihàn àti ìpolongo àwọn ohun àmúṣọrọ̀-ajé Ìpímlẹ̀ yíí fún àgbáyé rí nípa ṣíṣètò ìpàdé àpérò àti ìlanilọ́yẹ lórí ètò ọrọ̀-ajé láti fa ìfẹ́ àwọn olùdáṣẹ́-sílẹ̀ lábẹ́lẹ̀ àti lókè òkun wá sí Ìpínlẹ̀ yíí

## 3.00 OWÓ TÓ WỌLÉ LÁBẸ́LÉ.

- Iye Owó tó wọlé lábẹ́lẹ́ lọ́dún yìí tí iye rẹ̀ dín ní Bílíọ́nù mẹ́tàdínlógún Náìrá (₦16,748,259,539.93) ga ju ti ọdún 2021 ni iye owó tó lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù Mẹ́ta Náìrá (₦3,127,826,405.93) nígbà tí iye tó wọlé ní ọdún 2021 lé ní Bílíọ̀nù Mẹ́tala àbọ̀ Náìrá (₦13,620,433,129.00) Èyí fihàn pé ìlọsíwájú bá owó to wọ́le lọ́dún yìí ju ti ọdún tó kọjá lọ tó túmọ̀ sí pé òpin ti dé bá ọ̀rọ̀ Kòró (COVID-19) pátápátá.
- Bí àbájàde yíí kò ti wúni lórí tó, owó tó wọlé lábẹ́lé kàn gbé pẹ́ẹ́lí díẹ̀ nínú ìṣàmúlò ètò ìṣúná ní ìdá tó dín ní ìdá méjìléláàádọ́rùn-ún (91.81%) ní ọdún 2020 sí ìdá méjìléláàádọ́rùn-ún (92%) ní ọdún 2021. Iye tí owó tó wọlé lábẹ́lé fi gbé sókè láti ìdá mẹ́rìnlá lé díẹ̀ nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (14.19%) sí ìdá Mẹ́rìnlá àti ìpín mọ́kànlélọ́gbọ̀n (14.31%).
- Owó tó wọlé lábẹ́lẹ́ tí kìí ṣe owó- orí láti àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba (MDA's, Parastal and Tertiary Institution) àti Ilé-Ẹ̀kọ Gíga lọ́dún tí a ń gbé yẹ̀wò tí iye rẹ̀ dín ní Bílíọ́nù méje Náírà (₦6,865,932,509.57) pẹ̀lú ìṣàmúlò ètò ìṣúná tó jẹ́ ìdá mọ́kànlélọ́gọ̀rin (81.06%) Èyí gbé pẹ́ẹ́lí sí i ní iye tó lé ní ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta Mílíọ̀nù Náìrá (₦532,493,101.57) tó jẹ́ ìdá mẹ́jọ àti ìpín ogóji nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (8.40%) tí a bá fi wé ti ọdún 2021 tó lé ní Bílíọ́nù mẹ́fà Náírà (₦6,333,439,408.08)
- Owó tó wọ́lé láti ìdókòwò tí iye rẹ̀ jẹ́ ogún ẹgbẹ̀rún Náìrá (₦ 20,000) ni owó tó wọlé láti ibẹ̀ ni Ilé- Iṣẹ́ tó wà fún ètò ìfẹ̀yìntì jẹ́ ẹgbẹ̀rún méjìléláàádóje

àbọ̀ Náìrá (₦ 132,500). Èyí kọ Ilé-Iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó wò lóminú pé ogún ẹgbẹ̀rún Náìrá (₦ 20,000) péré ni owó tó wọlé lati orí ìdókòwò.

- Ó yẹ kí wọ́n ṣe àgbékalẹ̀ Igbìmọ̀ Apowó- wọlé láti ṣe ìjíròrò pẹ̀lú Ilé-iṣẹ́ Ìjọba **(MDAS)** láti ṣe àlàkalẹ̀ ọ̀nà bí owó yóò ṣe máà wọlé. Ìwé akọ́ọ́lẹ̀ olóṣooṣù lórí bí wọ́n ṣe pawó wọlé láti Ilé- iṣẹ́ Ìjọba ni wọ́n gbọ́dọ̀ máá mú ṣọwọ́ sí Ìgbìmọ̀ Apowó- wọlé nàà kí wọn sí ṣàlàyé ìdí tí owó kò fi wọlé nígbà tí owó kò bá wọlé. Ìgbìmọ̀ náà sí gbọdọ̀ tètè wá ojútùú sí àwọn ìṣòro tí Ilé-iṣẹ́ Ìjọba bá ń kọjú.
- Àròpọ̀ gbogbo owó-orí tó wọlé lọ́dún nàà dín díẹ̀ ní Bílíọ́nù Mẹ́wàá Náírà (₦9,882,327,025.36) tí iye owó tó dín ní Bílíọ́nù Mẹ́sàn-án Náírà (₦8,816,606,459.16) tó lé díẹ̀ ní ìdá mọ́kàndínláàádọ́rùn-ún (89.21%) jẹ́ owó- orí tó wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ Ìjọba (PAYE)
- Àwọn owó-orí tó wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn tí kìí ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba gbé pẹ́ẹ́lí si láti iye owó tó lé ní Mílíọ̀nù àádọ́rinlénígba àbọ̀ Náírà (₦270,660,107.00) ní ọdún 2021 sí iye owó tó lé ní Mílíọ́nù àádọ́rùn-ún dín méjìlénígba ábọ̀ Náírà (₦288,669,688.25) ní ọdún 2021. Èyí jẹ́ ìdá méjì nínú ọgọ́rùn-ún (2%) tó kàn gbé sókè díẹ̀ ju ti ọdún tó kọjá lọ tó dín díẹ̀ ní ìdá méji nínú ọgọ́rùn-ún (1.99%)
- Owó ìdàgbàsokè nínú owó tó wọlé lábẹ́lé lápapọ̀ lọ́dún náà lé díẹ̀ ní ìdá kan nínú ọgọ́rùn-ún (1.03%) Èyí lọ sílẹ̀ ju ti ọdún to kọjá tó lé ní ìdá méjì (2.27%) Èyí fihàn pé akitiyan àwọn Ilé-Iṣẹ́ tó ń powó wọlé lábẹ́lé kò kúnjú ìwọ̀n tó láti mú kí owó tó ń wọlé látọ̀dò àwọn tí kìí ṣe ọ̀ṣìṣẹ́ Ìjọba pọ̀ sí i. Ilé-Iṣẹ́ tó ń powó wọlé lábẹ́lé gbọ́dọ̀ ṣètò àlàkalẹ̀ tí yóò ṣe àgbékalẹ̀ àwọn tó ń sanwó orí, bí wọ́n ṣe ń san-an wọlé, owó-orí tí wọ́n san àti èyí tí wọn kò san. Ọ̀nà kan gbòògì tí owó-orí fi lè máa wọlé lọ́pọ̀ yanturu ni irú àlàkalẹ̀ báyìí.
- Mímú àwọn tí kìí ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba sanwó orí déédéé ni ìrètí àti mú kí owó-orí tó ń wọlé burẹ́kẹ sí i. Nípa báyìí, a gba Àjọ tó ń pawó-orí wọlé ní ìmọ̀ràn láti

ṣiṣé takuntakun láti mú kí àwọn tí kìí ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba máa sanwó-orí wọn déédéé

## 4.00 PÍNPÍN OWÓ SÍ ÀWỌN ILÉ-IṢẸ́ ÌJỌBA ÀTI ÀWỌN Ẹ̀KA ILÉ-IṢẸ́.

- A ṣe àkíyèsí pé owó-afisisẹ́ àkànṣe àti owó-iná ni a kò pín fún wọ́n bí wọn ti ṣe àlàkalẹ̀ rẹ̀. Àwọn Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba tí a ti ṣe àlàkalẹ̀ owó-ìná tí iye rẹ̀ dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù Méjì Náìrà (₦1,959,263,393.05) ni wọn kò fún ní owó kankan ni ọdún náà. Àwọn Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba mìíràn tí wọ́n ṣe àlàkalẹ̀ owó tí iye rẹ̀ dín ní ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀rún Mílíọ̀nù Náírà (₦437,438,675.48) ni wọn kò rí ju iye owó tó dín díẹ̀ ní Mílíọ̀nù Mẹ́rìn lé láàádọ́rùn-ún Náírà gbà (₦93,958,639.89) Èyí tó jẹ́ ìdá mọ́kànlélógún àbọ̀ dín díẹ̀ nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (21.48%).

## 5.00 ÀNÁLÉ OWÓ ÀWỌN ILÉ-IṢẸ́ ÌJỌBA ÀTI Ẹ̀KA ILẸ́-IṢẸ́

- Ànálé owó oṣù àwọn òṣìṣẹ́ Ilé-Iṣé Ìjọba márùn-ún jẹyọ nínú ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò. Èyí dára ju ti ọdún 2021 ti Ilé-isẹ́ Ìjọba mẹ́tàlélọ́gbọ̀n (33 MDAS) ni ànájù owó oṣu òṣìṣẹ́ tí iye rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù méjì àbọ̀ Náírà (₦2,680,550,622.21) ní ọdún tí à ń gbé yẹ́wò. Ìwé ọwọ́ fún ànálé owó wọ̀nyí ni wọn kò fi ṣọwọ́ sí Ilé Iṣẹ́ Ayẹ̀wó- Owó- Wò Àgbà ti Ìpínlẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí àgbékalẹ̀ òfin Ìjọba Àpapọ̀ tó rọ̀ mọ́-ọn (Section 120(2) of the constitution of Federal Republic of Nigeria, 1999(as amended).
- Iye owó tó lé ní Mílíọnù Méjì dín lọ́gọ́fà Náírà (₦118,113,621.88) ni wọ́n san gẹ́gẹ́ bí ànálé owó ìfẹ̀yìntì ní ọdún 2022. Ó yẹ kí wọ́n pèsè owó tó tó fún un tẹ́lẹ̀. Àwọn òṣìṣẹ́ tó ń ṣiṣẹ́ lórí ètò ìṣúná gbọ́dọ̀ fi èyí sọkàn nígbà tí wọ́n bá ń ṣe àgbékalẹ̀ ètò ìṣúná lọ́jọ́ iwájú.
- Àlàkalẹ̀ ìsọ̀rí owó fún ọdún 2022 fihàn pé Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba mẹ́rìnlá (14 MDAs) ní ànálé owó tí iye rẹ̀ dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù méjì Náìrá (₦1,819,047617.92) Eléyìí ga lọ́pọ̀ ju ti ọdún 2021 èyí tí Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba mẹ́jọ (8MDAs) ní ànálé

owó-ìná tó lé ní Mílíọ́nù mẹ́fà lé lọ́gọ́rùn-ún àbọ̀ Náìrá (₦ 106,690,596.87) Ìwé-ọwọ́ fún ànálé owó-ìná yìí ni wọn kò fi ṣọwọ́ sí Ilé-Iṣẹ́ Ayẹ̀wẹ́- Owó-wò Àgbà ti Ìpínlẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí àgbékalẹ̀ òfin Ìjọba Àpapọ̀ tó rọ̀ mọ́-ọn (Section 120 (2) of the constitution nof federal republic of Nigeria, 1999 (as mended).

- Ànálé owó àkànṣe iṣé tí Iye rẹ̀ dín ní Mílíọ́nù kan àbọ̀ Náírà (₦1,395,491,502.22) ní Ilé-iṣẹ́ Ìjọba (MDAs) méjì ná lé ni ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò yìí tí èyí sì pọ̀ ju ti ọdún tó kọjá lọ ní iye owó tó lé ní Mílíọ́nù mẹ́tàdínlọ́gọ́fà Náírà (₦ 117,369,580.05) Ilé- Iṣẹ́ ètò ìnáwó àti ti akọ̀wé owó Ìjọba gbọ́dò ṣe ìtọ́sọ́nà tó gbọngbọ̀n nípa ètò-ìṣúná láti dẹ́kun ànálé owó nínú ètò ìṣúná. Bákan náà, ìwé ọwó fún ànálé owó- ìná yìí ni a kò fi ṣọwọ́ sí Ilé-Iṣé Ayẹ̀wé- Owó- Wo Àgbà ti Ìpínlẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí àgbékalẹ̀ òfin Ìjọba Àpapọ̀ tó rọ̀ mọ́-ọn (Section 120 (2) of the constitution of Federal Republic of Nigeria, 1999 (as mended).

## 6.00 ÁWỌN OHUN ÌNÍ ÀTI GBÈSÈ

- Kò sí àjẹṣẹ́kù owó àkopamọ́ tí a ṣe àkíyèsí lópin ètò ìṣúná ọdún nàà nígbà tí àpapọ̀ owó tó ṣẹ́kù sí Báǹkì lópin oṣù kejìlá ọdún 2022 dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù Mẹ́wàá Náìrá (₦9,994,754,409.91)
- Ó ṣe Pàtàkì kí ètò tó múná dóko wà nípa ètò ìnáwó kí owó tó pọ̀ má kàn má wà lọ́wọ́ tàbí ní Báǹkì. Èyí máá jẹ́ kí a pàdánù owó tó yẹ kó wọlé lórí owó bẹ̀ẹ̀ láìfi dókówò. Bí ìgbà bá ṣe rí àti bí Náírà ṣe ń lọ sókè-sódọ̀ lágbáàyè yẹ fún àkíyèsí.
- Owóyáà Ìjọba Ìpínlẹ̀ látòkèèrè títí di ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n oṣù kejìlá ọdún 2022 (31st Dec, 2022) jẹ́ iye owó tó lé ní Bílíọ́nù márùn-ún dín láàádọ́ta àbọ̀ Náírà (₦45,541,058,812.00) nígbà tí owóyáà lábẹ́lé lé ní Bílíọ́nù mọ́kànlé-

láàádọ́rùn-ún Náírà. (₦91,342,575,044.30) Àròpọ̀ gbogbo owóyàá náà dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù Mẹ́tàdínlógóje Náírà (₦ 136,883,633,856.30)

- Àwọn gbèsè míìràn tí Ìjọba Ìpínlẹ̀ jẹ títí di ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n oṣù kejìlá ọdún 2022(31st Dec.2022) dín díẹ̀ ní Bílíọ́nù Mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n àbọ̀ Náírà(#27,454,552,968.07).Tí a bá ṣe àròpọ̀ gbogbo gbèsè náa papọ̀, yóò jẹ́ owó tó dín ní Mílíọ́nù mẹ́rìnlégọ́jọ àbọ̀ Náírà(#164,338,186,824.37).
- Àropọ̀ owóyáà (lókéèré, àti lábẹ́lé) tó wọlé fún Ìjọba Ìpínlẹ̀ lọ́dún tí a ń gbé yẹ̀wò yìí lé díẹ̀ ní Bílíọ́nù mẹ́tàlá Náírà (₦13,077,286,724.42) nígbà tí owóyáá tí Ìjọba Ìpínlẹ̀ san padà lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù méjìdínlógún Náírà (₦18,002,962,953.77) èyí ti iye tó lé ní Bílíọ́nù méje àbọ̀ Náìrá (₦7,525,372,997.68) jẹ́ àsanpadà ojú owó, tí Bílíọ̀nù mẹ́wàá àbọ̀ dín díẹ̀ Náírà (₦10,477,589,956.09) jẹ́ èlé owó tí wọ́n san ní ọdún 2022.
- Àkíyèsí Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò ní pé ní ọdún nàà gbèsè sí owó tó wọlé sí Ìpínlẹ̀ jẹ́ ìdá mọ́kànléláàádóje lé díẹ̀ (131.08%) títí di ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n oṣù kejìlá ọdún 2022 .Àdínkù ìdá tó lé ní ìdá mọ́kànlélọ́gbọ̀n (31.62%) bá èyí tí a bá fi wé ti ọdún 2021 tó dín díẹ̀ ní ìdá mẹ́tàlélọ́gọ́jọ (162.70%)
- Èrò Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò ní pé tí Ìjọba Ìpínlẹ̀ bá n tẹ̀síwájú láti máá gbẹ́kẹ̀lé ẹ̀yáwó fún ṣíṣétò ìnáwó fún ohun èlò amulo rẹ, gbèsè Ìjọba yóò kọjá àfaradà ní kòpẹ́-kò- jìnà
- Nípa báyìí Ìjọba nílò láti ṣe ìró lágbára fún àwọn ohun èlo amulo rẹ̀ nípa níní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwon Àjọ Aládàáni àti Ọlọ́danni láwùjọ

## 7.00 ṢÍṢE ÀMÚLÒ ÈTÒ ÌNÁWÓ TI IPSAS

- Ìgbésẹ̀ tó làmìlaka ni Ìjọba tí gbé nípa ṣiṣé àmúlò ètò ìnáwó tí (**IPSAS)** nípa gbígba Olùwádìí láti ṣe àgbéndè rẹ
- Ṣíṣe ìgbélé ọ̀ṣùwọ̀n fún ohun ìní èyí tó ṣe kókó nípa gbígbé ètò náà kalẹ̀ ni kò ì tíì wáyé.
- Àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ bí àwọn wọnlẹ̀-wọnlẹ̀ adíye lé dúkìá àti àwọn míìràn ní wọ́n gbọ́dò kópa nínú ìdíye lé ohun ìní láti mú àdínkù bá owó tí yóò ná Ìjọba

## 8.00 PÍNPÍN ÌDÁMẸ́WÀÁ OWÓ TÓ WỌLÉ LÁBẸ́LÉ SÍ ÀWỌN ÌJỌBA ÌBÍLẸ̀

- Ẹ̀tọ́ Ìjọba Ìbílẹ̀ ní ìdámẹ́wàá owó tó wọlé lábẹ́lè sí àpò Ìjọba Ìpínlẹ̀. Nì ọdún tí a ń gbé yéwò yíì, iye owó tí ó wọle lábẹ́lé gẹ́gẹ́ bí àkọ̀ọ́lẹ̀ Ilé- Iṣẹ́ tó ń ṣètò ìnáwó Ìjọba Ìpínlẹ̀ (Acountant General) dín ní Bílíọ̀nù mẹ́tàdínlógún Náírà (₦16,748,259,534.93), ìdámẹ́wàá owó yìí tó yẹ kó lọ sí àpò Ìjọba Ìbílẹ̀ jẹ́ iye owó tó lé ní Bílíọ́nù kan àbọ̀ Náírà (₦1,674,825,953.49) èyí tí wọ́n san iye tó dín ní ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta Mílíọ́nù Náírà (₦486,227,731.06) nínú rẹ̀ fún àwọn Ìjọba Ìbílẹ̀ tí ìyókù rẹ̀ tó lé díẹ̀ ní Bílíọ́nù kan Náírà (₦1,188,598,222.44) ni wọn kò san iye owó tó lé ní Bílíọ́nù kan Náírà (₦1,057,755,394.47) àti owó tó lé díẹ̀ ní Bílíọ́nù kan Naira (₦1,110,901,640.19) ní ṣisẹ̀ - n – tẹ̀lé ni odun 2020 ati 2021.Ó ṣe Pàtàkì kí wọ́n fún àwọn Ìjọba Ìbílẹ̀ lówó tó tọ́ sí wọn déédéé kí ìgbáyé gbádùn lè wà fún àwọn ènìyàn lẹ́sẹ̀kùkú

## 9.00 OWÓ TÓ SỌNÙ

- Iye tó lé ní ọgọ́rùn-ún lé méje Mílíọ̀nù Náírà (107,384,799) tí ó sọnù ní àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba tí ọ́rọ̀ kàn ni wọn kò kọbi- ara sí, tí àwọn òṣìṣẹ́ tó ń ṣètò ìnáwó ni àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba náà kò tilẹ̀ gbé ìgbésẹ̀ láti ṣàwárí owó nàà.

## 10.00 ÀWỌN ÌDÓKÓWÒ ÌJỌBA

- Àwọn ìdókówò méjì tí àpapọ̀ iye owo rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù kan Náírà (₦1,175,144,342.00) ti ó wà ní ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò yìí, èyí tí owó rẹ̀ kéré níye sí ti ọdún tó kọjá lọ ní iye owó tó lé ní ọgọ́rin mílíọ́nù Náírà (₦80,100,000) tí ti ọdún tó kọjá lé ní Bílíọnù kan Náírà (₦1,255,244,342.00). Àdínkù yìí wáyé láti Ilé-Iṣẹ́ Búlọ́ọ̀kì Ìrè tí iye owó tó wọlé láti ibẹ̀ dín láti Ọ̀tàlénígba lé méje Mílíọ́nù Náírá (₦267,000,000.00) ní ọdún 2021 sí ọgọ́sàn-án lé mẹ́fà Mílíọ́nù Náírà (₦186,900,000.00) ní ọdún 2022. Àwọn Ayẹ̀wẹ́-owó-wò kò rí owó kankan tó wọ àpò Ìjọba Ìpínlẹ̀ láti ibi ìdókòwò wọ̀nyí.
- Ohun ìní ìdókówò nàà lórí ìwé lé ní Bílíọ̀nù méjìlélógún àbọ̀ Náírà (₦22,523,420,102.10) títí di ọjọ́ kọkàn lé lọ́gbòn oṣú kejílà ọdún 2022 (31st Dec, 2022) lẹ́yìn áyọkúrò ọlọ́dọọdún tó lé ní ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta lé mẹ́ta àbọ̀ Mílíọ̀nù Náírà (₦ 503,699,951.06). Owó ìní ìdókówò nàà lori ìwé gbé pẹ́ẹ̀lí sí i lọ́dún tí a ń gbé yẹ̀wò láti owó tó lé ní Bílíọ̀nù méjìlá Náírà (₦12,227,972,500.00) ju ti ọdún tó kọjá lọ torí pé àwọn ìdókòwò tuntun wáyé lóduń náà. Bí owó kankan kò ṣe wọlé lórí ìní ìdókòwò yìí pẹ̀lú gbogbo owó tí wọn ń yọ lọ́dọọdún síbẹ̀ jẹ́ kàyééfì fún Ilé-Iṣẹ́ ayẹ̀wé-owó-wò.

## 11.00 ÀTÚNYẸ́WÒ ÌṢÀKÓSO ÌṢÈTÒ ÌNÁWÓ

- Ó yẹ kí wọ́n ṣe àtúnyẹ́wò ìṣàkóso ètò ìnáwó Ìjọba tí wọ́n ń lò báyìì ní ìbámu pẹ̀lú ètò ìṣàkóso ètò ìnáwó tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ ṣe kí wọn sì ṣe àgbékalẹ̀ kòkáárí Ilé-iṣẹ́ Àyẹ̀wò-owó-wò tí abẹ́lé (Central Internal Audit)
- Àwọn ìwé ìṣàkóso Ètò Ìnáwó kò sí lórí àtẹ fún rírà yálà ní Ilé- iṣẹ́ Ìjọba tàbí Ilé- Ẹ̀kọ́ṣẹ́ fún àwọn Oṣìṣẹ́ (Civil Service Commission or Office of Establishment and training).
- Kí ìwe ìṣàkóso Ètò Ìnáwó wà lórí ìkànnì Ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkìtì fún ànfààní àwọn tó bá nílò rẹ̀.

## 12.00 ÈTÒ ÌṢÀKÓSO LÁBẸ́LÉ

- Ètò ìṣàkóso lábẹ́lé tó múnádóko kò tó pàápàá fún Ilé-iṣẹ́ Àyẹ̀wé-owó-wò lábẹ́lé
- Àkọ́ọ̀lẹ́ àyẹ̀wò olóṣoosù Àyẹ̀wò-owó-wò lábẹ́lé láti àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba kò wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí a jíròrò lé lórí tẹ́lẹ̀
- Àkọ́ọ̀lẹ́ tó kúnjú ìwọ̀n tó sì báramu ni ó gbọ̀dọ̀ jẹ́ àkọ́ọ̀lẹ́ àyẹ̀wò olóṣoosù Àyẹ̀wò-owó-wò lábẹ́lé

## 13.00 ÀWỌN OHUN TÓ Ń FẸ́ ÀMÓJÚTÓ NÍ ILÉ-IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ TI ÌPÍNLẸ̀ ÈKÌTÌ

- Òṣìṣẹ́ kò tó
- Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdàgbàsokè àwọn òṣìṣẹ́
- Ètò ìnáwó
- Ọkọ̀ àfiṣìṣẹ́
- Ọ́fììsì fún àwọn òṣìṣẹ́

**Adéùyá, Victor Olúwọlé (ACArb, CFA, FCA)**
**FRC/2021/009/00000023353**
**Auditor-General,**
**Èkìtì State.**